# KABO O, KABIYESI. ALAIYELUWA KABIYESI O!!



*AWOGBA Omode fun Girl, Eti, Hiho - ehin, Owere. Ra Tire Ni Ile Egbogi*
*— ISE —*
*Oladunmi Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS*

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

*TO CLEAR*
*Gents Suede Court Shoe*
*Brown, Black & Grey*
*Before 50/- Now 42/6d*
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
*10A, Maloney Bridge St.,*
LAGOS.

VOL. VIII No. 452. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, JANUARY 28, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Kabo O, Alaiyeluwa, Kabiyesi!

Ọba Obinrin Elizabeth keji ni o jẹ olori fun United Kindom, South Africa Pakistan Ceylon, New Zealand, Australia ati Canada; on si tun ni ọba obinrin fun gbogbo ilẹ ti o wa ni abẹ abo awọn orilẹ-ede wọnyi. Gbogbo awọn enia ti o wa ni orilẹ-ede wọnyi ni wọn ntuba fun ọba, wọn a si ma ṣe eto ilu ni orukọ ade rẹ.

Ni ilẹ Gẹsi gan ni itẹ Ọba fi idi rin'ẹ si, ṣugbọn ni ilẹ miran ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ commonwealth laikn India, awọn Gomina agba ni o nṣoju fun ọba labẹ awọn alakoso ara ilu. Gomina agba yi ni o jẹ ẹniti nṣe akoso ilu gẹgẹbi ilana ofin ti a fi lelẹ, ijọba ilẹ Gẹsi ko si le lo agbara dandan kan lori eto iṣẹdalẹ yi.

Ni ilẹ Nigeria, Gomina agba ni o jẹ aṣoju ọba obinrin ilẹ Gẹsi ninu eto ijọba. Ninu awọn orilẹ miran ti o wa ni abẹ itọju ade ọba, awọn gomina, ati ajẹlẹ ni wọn jẹ aṣoju ninu eto ijọba pẹlu iranlọwọ awọn oṣelu, ati igbimọ ti o wa ni abẹ idari ijọba ilẹ Gẹsi fun ijoba rere ninu ilu.



THE NATIONAL BANK

Of Nigeria Limited.

Ọna tara ti enia legba lati di oniṣowo nilẹ Nigeria wa, ni ile ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Enikẹni ti o ba fẹ kan ogunlogọ aimoye awọn onisowo ilẹ Nigeria lara.
yala lati ma ta ọja fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa,
ki o lo si NATIONAL BANK

ILE IṢẸ WA NI EKO :—

37, Marina Street. P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## AGOGORO EYO



Awọran iru iwe wa yi niti Ẹyọ ti ao ṣe fi yẹ Alaiyeluwa Ọba obinrin ati Ọlọla nla Ọkọ rẹ si ni ọjọ ti wọn yio fi ilu wa silẹ pada lọ si ilu Oyinbo. A ṣe Asọiẹ-ọrọ diẹ ti ima jade lẹnu awọn ẹyọ fun anfani ẹnyin okawe wa.

(1) Moyọ fun ẹ
Moyọ fun rami 8mi alagbada okiki ọkọ Sadatu Hu-u-haba.

(2) Alẹlẹ e malẹ okunkun e makun birimu - birimu Hu-u haba.

(3) Emi ayọnpọntan bi ẹni nyan'de, Awo loku l'awo nsinku Awo. awọn Ọgberi a si ma sinku Ọgbẹri ni mọdẹ oraye.

HU-U-HAHA

## Apelewon Bi Ọbọ

Josaiah Atuore ni orukọ ọkunrin kan ti o sọ niwaju adajọ Kotu Ibadan, wipe on ti w'ẹwọn ni orisirisi ilu to igba ogun, (20 Times), o si nṣe ẹwọn ọlọdun marun-abọ lọwọlọwọ nilu Enugu.

Ọkunrin ilu-mọ'ka Ogbonikangi ọlẹwọn yi tun sọ wipe on jẹbi ẹsun ole afọ'le ti awọn fi on sun niwaju adajọ Ọgbẹni A. Majẹduumi nilu Ibadan.

Adajọ tun fi si ẹwọn ọdun meji-meji l'ori ẹsun kọkan ti awọn fi sun.

Apẹlẹwọn bi Ọbọ tara ni eleyi.

## IROHIN ILU OYINBO

### OLOYE TI EDINBURGH JE ENITI IGBE AIYE RE KUN FUN ISE

O to bi odun merin-le-logbon-le-ni-osu-mefa nisisiyi ti a bi oloye nla ti Edinburgh, ti ise oko Elizabeth keji nisisiyi ni erekusu Gorfu ti o wa ni agbeni Adriatic. Baba re. omo-oba Andrew je omo-oba Geoge kinni ti Greece. Oba Geoge kinni yi ewe, si tun je omo-oba Christian kesan ti Denmark. Nigbati omo oba Phillip ko ori ite sile lati wa ni abe ijoba ile Gesi, o di eniti o nlo oruko iya re Mountbatton.

Iya re ti a nwi yi si tun wa ni aiye on si ti ni omo oba obinrin ti Battenberg tele. Baba re so ara re di omo ile Gesi bii ogorun odun-o din-meji sehin.

Ni akoko ogun ajakaiye kinni ni baba re ko ori ite sile ti o si nje oruko Mountbatten. ko pe pupo ti ofi fi omo-oba obinrin Victoria se iyawo. Eyi si fihan wipe ninu eje kanna ni oba obinrin Elizabeth keji ati oko re yi ti wa,

### OLOYE EDINBUKG BI OLOGUN.

Oloye ti Edinburg je eniti o ni ife fun agbami, nigbati o bere eko re ni Scotland, gbaru ti o si fi ile-eko sile bi ogun-odun s'ehin, o di eniti o nkeko ni ile-eko awon omo ogun ti o wa l'agbami okun. Gegebi itan, gbogbo awon idile re ni o feran iru ise bayi, baba re papa si je oloye agba ri ninu oko ogun oju omi ti ile Gesi.



DUKE OF EDINBURGH

Ninu ogun, oloye Edinburg sise ninu opolopo oko ogun. Ni odun metala sehin, o si di ogagun kinni fun oko oju omi ti a npe ni 'Wallace'. Bi odun meji l'ehin eyi a tun fi se ogagun oko arumi 'HMS. whelp'. Ni odun marun s'ehin ni o di alase ati olu dari oko oju omi ti a npe ni Magpie. Oko yi wa ninu isowo karun pelu "HMS. Sparrow" ti o be etikun Nigeria wo laipe yi.

O to odun mejo s'ehin ti a fi lo wipe on ni yio fe oba obinrin Elizabeth keji, nigbati o si di ogunjo osu kokanla odun na, a so won po ninu igbeyawo mimo ni Westminster Abbey. Nigbati won gbe iyawo tan ni ijoba Gesi

(wo yoku loju ewe kefa)


# AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN FI YE WA WIPE

BI A BA NFI EGBOGI






COLGATE DENTAL CREAM FO EHIN

KO NI JEKI EHIN ENI BAJE, O DA RA PUPO



Ise ti egbogi yi nse ni wipe, eyiti o nho bi ose yen, yio wo gbogbo pala-pala ehin, yio si yo gbogbo ajeji kuro, ko ni jeki enu run, ko si ni jeki ehin baje.




O njeki ehin funfun, enu ko si ni run mo.


No/14

## Presentation Of Colours By Her Majesty The Queen To The 2nd Bn., Nigeria Regiment.

A number of seats have been allocated to ex-servicemen for this ceremony. Ex-Servicemen who wish to attend should apply to Headquarters, N.E.WA., 20, Campbell Street, Lagos together with their discharge books or other means of identification.

Tickets will be issued on the principle of "first come, first served."

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ELETI - OFE LAGOS"
Phone 23370

VOL. VIII. NO. 452. LAGOS, SATURDAY JAN. 28, 1956.


## Igboran San Ju Ebo Lo

Gẹgẹbi gbogbo nk an ti nṣe rọnyin- rọnyin nisisiyi, ti ipalẹm ọ ati ki Alaiyeluwa Ọba Obinrin pẹlu Ọlọla nla ọkọ rẹ ku abọ si ilu wa ni ọjọ Satide ti oni yi, ni a ṣe gbiyanju lati ṣi ẹnyin ọkawe wa leti l'ori ikilọ ti ọga ọlọpa ṣe.

Ikilọ na ni wipe, ni gbogbo asiko ti Alaiyeluwa ọba Obinrin yio lo ni ilu wa nihin, ki olukuluku ṣe itọju ile rẹ nitoripe ko ni si ọlọpa to lati ṣe abojuto gbogbo ilu ni asiko ti nwọn ba nilati ṣe itọju ọpọ enia, ni ara ilu Eko ati awọn ilu agbegbe Eko ti nwọn yio ya wọ'lu lati le fi oju ri alaiyeluwa Ọba Obinrin.

Ẹṣọra gidigidi, ṣe ẹnyin na ti mọ iṣẹ awọn ọmọ jaguda nigbati iru ariya ti ko tilẹ to iru eyi ba nṣe larin ilu wa.

O di ọwọ yin o,
Igbọran san ju ẹbọ lọ.

No 16

## POLICE NOTICE

### Sunday 29th, January - Cathedral Service, Road Closing Time Table.

The following roads will be closed for the periods stated on the occasion of Her Majesty the Queen and His Royal Highness the Duke of Edinburgh attending the Myohaung Day service at the Cathedral Church of Christ at 9. 30 a. m.

| Date | Road | Lenth affected | Time | |
|---|---|---|---|---|
| | | | From | To |
| 29. 1. 56 | Brook Street, | Marina to Broad St | 8 a.m.- | 11. a.m |
| | Cable Street, | " " " " | " | " |
| | Campos Street | " " " " | " | " |
| | Joseph Street | " " " " | " | " |
| | Marina | Force Road to Kakawa St | " | " |
| | Odunlami Street | Marina to Broad Street | " | " |
| | Tinubu Street | Marina Kakawa Street | " | " |

CAR PARKS-FOR INVITED GUESTS ONLY.

(1) Odunlami Street.
(2) Tinubu Street.
(3) Marina

The general public may park in any Street, other than those above provided no obstruction is caused.

BICYCLE PARK-GENERAL PUPLIC

A bicycle park is being established in the courtyard of the C.M.S. Boys Grammar School in Broad St.

V. A. COVEYDUCK
ASST. SUPT. OF POLICE
MOTOR TRAFFIC DIVISION, LAGOS

## Lowo Iku Ina Oluwa Rere Gbawa

Kabba—A gbọ wipe ina nla ṣẹlẹ nilu Kabba ninu ọsẹ tokọja a si gbo wipe ina na jo ọmọbinrin bi ọmọ ọdun mẹwa kan pa, iya ọmọ na f'arapba ina pupọ.

Nwọn ni dukia ti o ṣofo sinu ina na to ẹlẹgbarun ponun. (£10,000),

Lọwọ iku ina, Oluwa rere gba wa.

## Ọko Ogun De Si Ebute Eko

A gbọ wipe ọkọ Ogun pataki kan ti a npe ni H.M.S. Magpie ti de si Ebute Eko nihin lati ki Alaiyeluwa Ọba Obinrin ati Ọlọla nla ọkọ rẹ ku abọ si ilu wa.

Ohun ti a nfẹ tọkasi ni wipe ọkọ ogun yi ni Ọlọla nla ọkọ Ọba Obinrin ti a npe ni Duke of Edinburgh ṣiṣẹ ninu rẹ gẹgẹbi alaṣẹ pataki "Admiral" ki o to ṣe igbeyawo.

Ọkọ na l'o de si ebute wa nihin, ẹ ṣe kabiyesi janma, fun ọba alaṣẹ ekeji Oriṣa.

## Esi Ibere

Olotu,

Inu mi ibadun pupọ lati sọ idahun ọrọ Ọgbẹni wa Mr. Solomon Balogun (Alias Toff) ti o sọ wipe, tani agba ninu awọn ọrẹ mẹta.

Ohun ti emi ro nipa ọrọ na ni pe Ọgbọn, Oye ati lakaye yẹn, nipe ti enia ba ni Ọgbọn ati Oye laisi Lakaye, asan ni.

Nitorina, Ọgbọn ati Oye okun lakaye ni awọn mejeji fa waiye. Nitorina lakaye ni agba.

Ejọwọ ẹniti o ba ni on tun mọ eyi ti o tun ya tọ si eleyi ki o jẹki ngbọ lọsẹ to mbọ.

Mo dupẹ pupọ, Olotu, ọwọ yin yio ma ro ke.

Emi ni
B.S Aisi Owo
Baba ijaya

No. 17

## POLICE NOTICE

### Closing Of Roads - Wednesday, 1st February, 1956

Her Majesty the Queen and His Royal Highness the Duke of Edinburgh will leave Government House at 8. 30 a. m. and drive to Ikeja Airport

| ROAD | LENGTH | TIME | |
|---|---|---|---|
| | | FROM | TO |
| Marina | Force Road to Balogun Street | 7. 30 a. m. | 9. 40 a. m. |
| Balogun Street | Marina to Ereko Street | 7. 30 a, m. | 9. 40 a. m. |
| Ereko Street | Balogun Street to Idumota | 7. 30. a, m. | 9. 40 a. m. |
| Idumota | Ereke Street to Carter Bridge | 7. 30 a. m. | 9. 40 a. m. |
| Carter Bridge | ALL | 7. 30 a. m. | 9. 40 a. m. |
| Denton Causeway | ALL | 7. 30 a. m | 9. 40 a. m. |
| Cifford Street | ALL | 7. 30 a. m. | 9. 40 a. m. |
| Prlince Edward Ave. | ALL | 7. 30 a, m. | 9. 40 a. m. |
| Ikorodu Road | Yaba Roundabout to Maryland Convent | 7. 30 a. m. | 9. 40 a. m. |
| Ojo Street, Ikeja | | 7. 30 a. m. | 9. 40. a. m. |
| Richards Avenue, | | 7. 30 a. m. | 9. 40 a. m. |
| Ikeja | | 7. 30 a. m. | 9. 40 a. m. |

CAR PARKS

Car parks for guests invited to the Airport will be as follows:-

| LETTER | COLOUR | PLACE |
|---|---|---|
| K | Red | Airport, by V. I. P. Hut |
| K | Blue | Airport, on main car park |
| K | Green | Airport, in Country Club Road |

The public is advised that as the Marina will be closed on occasion there will be no deliveries from Costoms Wharf, Lagos untill 9. 30 a. m.

V. A. COVEYDUCK.
ASST. SUPT. OF POLICE.
MOTOR TRAFFIC DIVISION, LAGOS.

## Irora Lakuregbe

Iwosan rẹ lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwosan ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe, o yẹ ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindinrin oluwa rẹ ko ṣiṣẹ to, o nfẹ iranlọwọ. Nitori iru amodi bayi lati ṣe jegbogi DE WITTS, yio si fun enia ni igbadun ara.

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nṣe iwosan Lakuregbe, danwo, ki o lọ ra ọkan ni ṣọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba ṣiṣẹ tara, ṣugbọn bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio de si oluwa rẹ, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti ṣiṣẹ. Danwo lọ ra ni ṣọbu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**

for Kidney and Bladder Troubles


## Ijo Eleto Se Ipade

EKỌ. Ipade Igbimọ ọdọdun ti Ijọ Eleto (Methodist Synod) bẹrẹ ni Eko ni ọjọ Aje tokọja ti iṣe ọjọ kẹrindin-logun oṣu kinni ọdun 1956, yi.

Alufa Agba E.J. Jones ni a yan ni Alaga fun ọdun 1957 dipo Alufa J.A. Angus a si tun E.A. Fowode yan ni akọwe Igbimọ.

Igbimọ na si ṣe ipinnu fun Ile-ẹkọ Giga ti yio ma jumọ kọ awọn Alufa fun Ijọ ti C.M.S. ati ti Eleto fun ilẹ Nigeria.


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS

## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to şeşe de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.

## FUN TITA

ERO ITẸWE KEKERE (4 BANK) AFA-DANI

| | |
|---|---|
| Ti Corona | £12. 10. 0 |
| Ti Empire Aristrocrat | £14. 10. 0 |
| Ti Imperial | £16. 10. 0 |

ERO ITẸWE NLATI A NGBE LE ORI TABILI.

| | |
|---|---|
| Ti Oliver (3 Bank) | £5. 10. 0 |
| Ti Empire (3 Bank) | £6 10. 0 |
| Ti Remington Tabi Underwood (4 Bank) | £11.10.0 |
| Ti Imperial (4 Bank) | £14.10.0 |
| Awọn Eya miran (4 Bank: Ti o wa Ni'lẹ | £8.10.0 |

*ALDERSHOT WAREHOUSES LTD., POUND ROAD, ALDERSHOT ENGLAND*

NOW OPEN!

NIGERIA'S 3 Super Service Stations

Double Powered Mobilgas
Double Protection Mobiloil ★
Mobilubrication

24 hours service ★

★ Automatic car washing polishing, waxing and vacuum cleaning at Mobil Service Mart, Lagos

★ Emergency Road Service day or night

Auto Accessories and batteries ★ battery servicing Goodyear tyres Tyre repairs.

★ Credit customers of Kingsway Stores may charge products and services, excepting Mobilgas purchased at Mobil Service Mart, Lagos, to their Kingsway account

MOBIL SERVICE MART
Martins Street
Lagos

MOBIL SERVICE MART
Oyo Rd. Mokola
Ibadan

MOBIL SERVICE MART
Corner of Park and Asa Streets
Aba

**Mobil Oil NIGERIA LIMITED**

## Enu Pa Elenu

Lati Ọwọ ẸṢỌ IKOYI

Aka - heregbe - difa, ọmọ awo Orunmila, Akanrigi - difa, ọmọ awo Ọrunmila, Adubulẹ - difa. Awọn mẹtala nwọnyi lo nṣe ọmọ awo Ọrunmila. Lọjọ ti a ran wọn lọ sinu aiye, ti nwọn de ohun tan, ti nwọn ko bere oluwa wọn. Otura - Orikọ.

Awọn ọmọ awo Ọrunmila nwọnyi lo fi ẹnu ara wọn pe ifa ti o lọ wọn lọrun pa yi. Eyi ni idi rẹ ti awọn Babalawo ṣe npe Ọrunmila ni iku dudu atẹ lẹwọ. Nigbati odu Ifa Otura - Orikọ bu fu soju ọpọn Awo kan, lẹsẹ kanna babalawo na yio yara fi ọwọ mejeji gbe ọpọn ifa na soke lati fi jẹwọ wipe, ope ni on nṣe, nitori ki o ma ba ku ni warawara. Bi itan odu Ifa Otura - Orikọ yi ti lọ niyi.

Awọn ẹni mẹtẹta nwọnyi, Akaheregbe - difa - Akanrigi - difa ati Adubulẹ difa ti kọ iṣẹ Babalawo lọdọ Orunmila, nwọn si ti kọ ifa pari Oru nmila ran ọkan lọ silu Ilara, ọkan lọ silu Ijero ati ẹkẹta lọ si Illa Ọrọgun. Nigbati nwọn de ọhun, nkan ṣe ẹnure fun wọn tobẹ ti nwọn ko tilẹ ranti ẹniti o ran wọn niṣẹ mọ.

Lọjọ kan, Ọrunmila de ara rẹ mọ inu apẹrẹ, o ni ki a gbe on lọ sọdọ Akeheregbe - difa. Nigbati nwọn de ibẹ, nwọn sọ apẹrẹ kalẹ, nwọn ni Oluwa rẹ ni rẹ ni ki a gbe apẹrẹ yi fun ọ. O poṣe lọ ṣara, o wipe nibo, ni on yio gbe apẹrẹ nla yi si. On ko tun ni baba kan mọ lẹhin ti on ti kọ ifa pari. Bi o ti sọ gbolohun yi jade, bẹni Ọrunmila fo jade lati inu apẹrẹ, o si bere pe Ifa kini eyiti o da loni, o si dahun pe Otura - Orikọ Bi o ti wi bayi tan ọrun rẹ yin sẹhin, o si ku.

Ọrunmila tun bọ sinu apẹrẹ, o ni ki aru on lọ sile Akanrigi-difa nigbati nwọn sọ ẹru kalẹ tan, nwọn jiṣẹ fun wipe Baba rẹ ni ki a gbe apẹrẹ yi fun ọ, on na papa tun poṣe lọ ṣarara, o si wipe, on ti di gende fun ara on, nibo ni on gbe tun ni baba kan si. Ọrunmila fo jade lati inu apẹrẹ, o bere lọwọ rẹ wipe Ifa kini eyiti o da silẹ. o si dahun wipe Otura-orikọ ni. Lẹsẹkanna, ọrun rẹ yin sẹhin on na si ku. Adee mọ inu apẹrẹ, o ni ki aru on lọ sile adubulẹ-difa

Nigbati o de ibẹ, o ba nibiti o ndifa lọwọ, Ọrunmila tun yọ si, o bere wipe, Ifa kini eyiti o da ni? Adubulẹ difa dahun wipe, ye! Baba mi, nko mọ ifa na o, titẹ ni mo kan tẹẹ ṣ'oju ọpọn, o si yara gbe ọpọn na soke si Ọrunmila ki o le ba on woo.

Nigbana ni Ọrunmila wipe, iwọ ti o jẹwọ ope tirẹ fun mi yi ni ọmọ mi njẹ yara wa nisisiyi ki nran ọ lọ si Ilefẹ Oyẹlagbo. ki o wi fun wọn pe, iku de si awọn ọmọ werẹ ibẹ lọdun yi, oromọ adiẹ ati ọkanlerugba ni ẹbọ Adubulẹ-difa si ṣe bi a ti sọ fun, o si ko gbogbo etutu wa jẹ fun Ọrunmila. Ni amọdun Ọrunmila tun ran lọ sile Ifẹ wipe iku de lọdun ni si gbogbo awọn giripa Ifẹ, obukọ kan, ati ọtalelẹgbẹta ni ẹbọ, Adubulẹ-difa tun lọ o si ko gbogbo ohun etutu na wa fifun Ọrunmila. Lọdun keta Ọrunmila tun ran Adubulẹ difa sile Ifẹ wipe iku de si gbogbo arugbo lọdun ni, agutan kan, ati ogbonkanla ni ẹbọ, o lọ o si ko gbogbo etutu na wa jẹ fun Ọrunmila

Lẹhin eyi, Ọrunmila fi ọwọ le Adubulẹ-difa lejika, o si wi fun pe, lati oni yi lọ, bi etutu ba da bo ẹnikan lara, ti awọn si sare wa sọdọ rẹ ki o gba wọn, sọ fun wọn pe, ki nwọn mu eko o mọ ogoji ki nwọn wa gba ifa ki nwọn si mu ohun gbogbo ni mejimeji: Alafia yio de si oluwa rẹ.

...yani, o ri i, awọn Babalawo npaṣẹ wipe ki enia wa gba ifa, tabi ki ala-san wa wo Igbodu.

## Ipade Apapo Egbe Onisegun Agege

Lati Ọwọ J.S. Oloyede (Akọwe Ẹgbẹ)

AGEGE— Awọn ẹgbẹ Onişegun ni Agege ati gbogbo agbegbe rẹ ṣe ipade ni ilu Agege ni ọjọ Satide ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu January, 1956 yi, ipade na miringindin, o pa bambari.

Awọn ẹgbẹ Onişegun yi ti bẹrẹ ninu ọdun 1925, ti awọn ẹgbẹ na si ti nṣe iṣẹ iwosan ribiribi fun oniṣirişi arun ti ima yọ ọmọ enia l'ẹnu ni ode aiye awọn ẹgbẹ na siti gba iwe aṣẹ (Registered) lọjọ ti o ti pẹ, nwọn si nfi gbogbo agbara ati imọ wọn ṣe iṣẹ ti Iṣẹ wọn na si ma nyọri pereregede.

Ninu ipade yi, awọn ẹgbẹ ṣe apero lori ohun pataki meji, ekini: ibiti nwọn yio ma pesi ṣe aşaro bi nkan ylo ti ma ṣe lọ dede ati ekeji ni wipe; o tọ o si yẹ ki Ijọba - Iwọ-Orun mọ wipe ti ijọba Iwọ orunni ẹgbẹ yi nṣe nitoripe ọmọ ilẹ enia dudu ni awọn ẹgbẹ na jẹ ati bi nwọn ti jẹ ogbonlkangi Onişegun to yi. o yẹ ki Ijọba Iwọ – Orun ni Nigeria mọ wipe wọn ni ọmọ ni Agege ati ẹkun rẹ.

Kabiyesi, awa l'ori balẹ fun Ijọba Iwọ Orun,a si fi eyi ki Alaiyeluwa Oba Obinrin ati ọlọla nla ọkọ rẹ pe nwọn ku abọ o ati pe alafia ni nwọn o si fi pada lọ si ilu Oyinbo. Amin

Awọn ẹgbẹ ti o ṣe ipade na ni.

1. Ẹgbẹ Ilupeju
2. Ẹgbẹ T'aiyeṣe Majẹobajẹ
3. Ẹgbẹ Maiyegun
4. Ẹgbẹ Ekitiparapọ,
5. Ẹgbẹ T'obalaṣẹ,
6. Ẹgbẹ Ọlọmọwẹwẹ
7. Ẹgbẹ Ifẹlodun,
8. Ẹgbẹ Alagbo - ọmọ
9. Ẹgbẹ Ilupaşi,

A ṣe ipade yi ni ile Ọgbẹni Abiọna, Basegun agba ni Atobajẹ Agege, nigbati ao ba tun ṣe ipade nla, ao sọ fun aiye gbọ.

## IROHIN ILU OYINBO

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

wa fi oye ati ọla ṣe ni ọṣọ, eyiti o jẹ ki wọn le ma pe ni ẹni-ọla olaye giga. Lati igbati iyawo rẹ ti gun ori itẹ, ko ṣe akitiyan pupọ mọ nipa awọn ọkọ ogun oju omi, kakabẹ nṣe lo di baba ẹgbẹ fun ọpọlọpọ awọn ohun ti o ṣe iyebiye ti a da silẹ ni ilẹ Gẹsi.


A SỌ ENIA KUKURU DI GIGUN

*Bi iwo ba fe Gun bi iwon Esun Meji de Mefa. Lo Ilana Titun ti a Sese Se.*

*O DARA FUN T'okunrin-T'obinrin.*

*Ofe Ni Ao Fi Fun. Kowe Si*

*ACTIVITES. (D 112)*

Kingsway, Delhi-9 India


No. 13

## Award of Federal Government Scholarships and Bursaries 1956-57

The Federal Government proposes to offer bursaries and scholarships to become available in the years 1956/57, and tenable at the University College, Ibadan, and at the three branches of the Nigerian College of Technology, for courses beginning in October 1956; of tenable at Collegesand institutions in the United Kingdom for courses beginning in 1957.

Persons wishing to apply for these bursaries and scholarships are reminded that the closing date for applications is the 31st March, 1956. Full details of the conditions and method of application are contained in Government Notice No. 88 published in the Nigeria Gazette No. 4 of the 19th January, and to be repeated in the Gazette of the 26th January, 1956.

No. 19

# POLICE NOTICE

CLOSING OF ROADS- TUESDAY, 31ST JANUARY, 1956

1. Her Majesty, accompanied by His Royal Highness the Duke of Edinburgh, will arrive at the House of Representatives at 10.09 a.m.

Her Majesty will leave the House of Representaves and return to Government House Via Racecourse Road, King's College Road and Cable Street at 10.30 a.m.

| ROAD | LENGTH CLOSED | TIME FROM | TIME TO |
|---|---|---|---|
| Marina | Kings George V Road to Brook Street | 9 a.m. | 11 a.m |
| Force Road | Marina to Moloney Street | 9 a.m. | 11 a.m |
| Racecourse Road | Force Road to Prison Street | 9 a.m. | 11 a.m. |
| King's College Road | Racecourse Road to Cable Street | 9 a.m. | 11 a.m. |
| Cable Street | King's College Road to Marina | 9 a.m. | 11 a.m. |

2. Her Majesty, accompanied by His Royal Highness, the Duke of Edinburgh, will leave Government House at 5.24 p.m. and drive to the Federal Supreme Court Via the Marina, Force Road and Racecourse Road.

She will return to Government House at 6.45 p.m. Via Racecourse Road, King's College Road, Cable Street and the Marina.

| ROAD | LENGTH CLOSED | TIME FROM | TIME TO |
|---|---|---|---|
| Marina | Force Road to Cable Street | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| Force Road | Marina to Moloney St. | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| Racecourse Road | Moloney St. to Prinson St | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| King's College Road | Racecourse Road to Cable Street | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| Cable Street | King's College Road to Marina | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| Hawley Street | Igbosere Road to Racecourse Road | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| Oke Suna Street | Igbosere Road to Racecourse Road | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| Strachan Street | Igbosere Road to Racecourse Road | 4.30 p.m. | 7. p.m. |
| Hunter Street | Igbosere Road to Racecourse Road | 4.30 p.m. | 7. p.m. |

V. A. COVEYDUCK,
Asst. Supt. of Police,
Motor Traffic Division, Lagos.




Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS

Read this list of popular titles

J. 2. 5811 Woru/Ladun Ladun)
" 5812 Igba Laiye/Mojn)
Basiru Alamu'u and
His (Apala) Band.
" 5813 Ka ma Lufin/Ore Otito kosi)
" 5814 Amolese/Fowo Kewe)
Eddie and His Melody Orch.
" 5822 Adie Oranyan/Alaimowe
Basiru Alamutu.
" 5859 Asiko/Alake - Lagos
Day Orchestra.
" 5851 Ologbon/Adekunle Alabi)
" 5852 Abanije/Raji Mustafa )
S. Aka and His Sakara
Orchestra.



J.2. 5869 St. Peter's School/Lasisi
Adeoti
" 5870 Njemanze/Nimota
Amoke
Aminu Olaribigbe
" 5871 Edolo Nosika/Eyinase-
igha-Ijaw Youths' Orch.
" 5885 Ope Fun Oluwa/Olorun-
nisola)
" 5886 Nosiru Seidu/Ore Meji)
" 5903 Iran Sabarumo /Ipari
Aiye)
Baby Face Mambo Orchestra.
" 5907 Nwaobi/Eda - Rosy
Show Mambo Orch.
" 5908 Ojure/Asa Kasa -
Aminu Olarigbe.
" 5911 Odele/Odun - Mo y ll
Ad sa's (Were), Band.

Sold by all the best stores

"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS

No 23

# REGISTRATION OF BUSINESS NAMES

In other to facilitate the process of registration, all applications for Registration of Business Names emanating from persons resident outside the Federal Territory of Lagos and the Southern Cameroons, should, in future, be addressed to the Principal Commercial Officer, Federal Department of Commerce and Industries, Kano, Port Harcourt or Ibadan, according to the Region in which the applicant resides.

Applications from persons residing in Lagos and the Southern Cameroons should continue to be addressed to the Registrar of Business Names, Federal Department of Commerce and Industries, Lagos.

J. E. B. Hall
Registrar of Business Names
Acting Director of Commerce and Industries

Lagos, 31st December, 1955.


## ARADAN NERVIGORA



Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, isokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati itufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na nan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹsẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d. e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores**

114, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.

## ADAMUORISA PLAY

FOR YOUR

„ELEYA"

(SHAWL FOR COVERING FACE)

Size 66 x 68

at 13/-

Call at:–

**A. B. AKINYEMI**

FACTOR (U.A.C. HABERDASHERY)

10A Moloney Bridge Street, Lagos

Phone: 23396

## GOD SAVE THE QUEEN

## MOBIL OIL NIGERIA LIMITED

**extends loyal greetings to Her Majesty the Queen and H. R. H. The Duke of Edinburgh**

## Welcomes Her Majesty The Queen

## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street, P.O. Box 487 Lagos Phone [illegible]